# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 705 WEDNESDAY, MAY 27, 1964 (2D)


## OLUBADAN WAJA !

IBADAN:- Ariwo nla ta, okiki si kan kakiri gbogbo orilẹ-ede Naijiria titi de Oke-Okun ni kutukutu owurọ ana ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kerindinlọgbọn oṣu yi pe Alaiyeluwa Ọba Issac Babalọla Mabayọjẹ Akinyẹle, Olubadan Ọba Ibadan filẹ-ṣaṣọbora.

Lẹsẹkẹsẹ ti Ọba oninure na yio pa ipo da lana, ni awọn ẹmẹwa Ọba ati awọn Ọmọ-Ọba ti bẹrẹsi tẹ waya si gbogbo awọn Ọba, Ijoye, Minista ati awọn ọmọ-oloku kakiri Naijiria ati oke-Okun pe, "KABIYESI ALAIYELUWA ỌBA WAJA LONI, Ẹ MAA BỌ WALE O"

Irohin fi ye wa pe ninu ọdun 1882, ni nwọn bi Ọba Alaiyeluwa na, O jẹ Oye Balogun Ibadan ninu Ọdun 1953, O si di Ọba Ibadan ninu Ọdun 1956, Ile ẹkọ C, M, S. Grammar School Eko lo ti ka iwe osi ku nigbati odı ẹni ọdun mejilelọgọrin (82 years) laiye

Irohin fi ye wa pe ni ọjọ mẹrin ọjọ Abamẹta ti iṣe ọgbọnjọ oṣu yi ni nwọn o sın oku Ọla oninure na.

Gbogbo awọn enia sarakisaraki ni awọn ti uranṣe ibanikẹdun si awọn ọmọ ati enia idile Ọba rere na.

## Awọn Oṣiṣẹ O Ha Da Iṣẹ Silẹ Loni Bi ?

# APAPỌ IJỌBA KUNA LATI MU ILERI WỌN ṢẸ

### Abayọri Igbimọ Iwadi Ẹkunwo Oṣu Awọn Oṣiṣẹ Ku Ọsẹ Meji

EKO:- Gbẹgẹdẹ gbina ninu ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria nibiti Ọgbẹni J. C. Ọbande, Minısta Alamojuto eto idasilẹ iṣẹ fun Apapọ Ijọba Naijiria gbe mba awọn Asiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ jakejado orilẹ-ede yi sọrọ lori Igbimọ iwadi ẹkunwo oṣu ati owo ọya awọn osiṣẹ sọrọ lana ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrindinlọgbọn osu yi.



Alhaji Adebola

Ni deede agogo mẹwa owurọ ni ipade na ti bẹrẹ, ṣugbọn awọn oṣiṣẹ Asiwaju Igbimọ ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ti de inu ile na ni deede agogo mesan owurọ.

Sugbọn nigbati ipade na bẹrẹ, Ọgbẹni J. C Ọbande ṣe alaye pe, Apapọ Ijoba Naijiria ko le gbe abayọri eto Igbimọ oluwadı ẹkunwo oṣu ati ọwo ọya jade gẹgẹbi ileri ti Ijọba ti ṣe lori ọrọ na.



Oloye J. M. Johnson

Şugbọn Ọgbẹni Ọbande ṣe ıleri pe, on yio sa gbogbo agbara ti Apapọ Ijọba fi si ıkawọ on lati ri i wipe abayọri eto Igbimọ oluwadi na jade fun gbogbo aiye gbọ.

Minista na tọrọ gafara lọwọ awọn aşiwaju Igbimọ ẹgbẹ awọn Awọn oṣiṣẹ fun aıko le mu ileri tı nwọn ṣe ni akoko ti Ijọba ko si le mu ṣẹ.

Lẹhinna ni Minista na tun wa ṣe akọtun ileri pe, ki awọn Asiwaju Igbimọ ẹgbẹ oṣelu na o tun fun Ijọba ni ọsẹ meji si i ki Apapọ Ijọba o le fi pari iṣẹ ti nwọn nṣe lori abayọri Igbimọ iwadi owo-oṣu na.

Şugbọn ki o to pari ọrọ rẹ ni Ọgbẹni Michael Imodu, ọkan ninu awọn Asiwaju Igbimọ ẹgbẹ awọn oşiṣẹ, ba dide, ti o si naro mọ Minista na.

Ninu ọrọ rẹ, Ọgbẹni Imodu sọ pe, Apapọ Ijọba fẹ mu awa oşiṣẹ ni omugọ nı tori suru ti a ti nṣe fun wọn lati iye ọjọ yı wa,

"Gbogbo enia ti Ori wọn ba pe, ti nwọn si ni arojinlẹ ni yio gba pẹlu mı pe, awọn Oṣişẹ ti ni suuru to fun Apapọ Ijọba Naijiria, şugbọn Apapọ Ijọba fẹ mu awọn ni "Igan" nwọn si fẹ ma a fi Ọbọ lọ awọn Oşişẹ.

"A ti şe wọn iba suru ti a le şe mọ fun Apapọ Ijọba, nwọn sọ pe o di Ọsẹ meji ki abayọri na o to jade nigbati a şe ipade, şugbọn Ọsẹ meji na ti pari ni ana, ẹ tun sọ pe kı a fun nyin ni Ọsẹ mejı miran,"

O wa pari ọrọ rẹ pe, "O jẹ ohun ıtiju lati ri ohunti Apapọ Ijọba se si awọn osisẹ o si dabi ẹnıpe ọwọ yẹpẹrẹ ni Ijọba fi mu awọn oşisẹ."

Ọgbẹni Wahabi Good Luck se alaye pe, "o dabi ẹnipe Ijọba fẹ maa lo awọn osisẹ bi ilo omı ojo eyiti o wọle wa bani ti a ko lọ si odo lọ pọn"

Alhaji Adebọla sọ pe. "oju wo ni nwon fẹ ki awọn osisẹ ti nwọn ti nretı abayọri eto ẹkunwo osu na ki o maa fi wo awọn gẹgẹbi Asiwaju.?"



Ọgbẹni Michael Imodu.

Ni ipari ọrọ rẹ ninu ipade na, Alhajı Adebọla sọ pe, "Apapo Ijoba ti kuna lori ilerı tı nwọn se fun awon osisẹ ohun ti o ba si sẹle lẹhın ikuna yi ohunkohun ni o le şẹlẹ."

Ọgbẹni Ọbande wa rọ awọn enia na pe, on ko sọ pe ọsẹ meji mọ, şugbọn ki nwọn fun Ijọba ni ọjọ mẹwa pere lati pari eto na.

Lẹsẹkẹsẹ ti awọn Asiwaju Igbımọ ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ na jade ni nwọn ba lo şe ipade pajawiri kan,

Agberoso awon Asıwaju ẹgbẹ oşişọ kan so fun Ejon'


Wo Oju Ewe Kẹfa




Ọgbẹni J. C. Ọbande

## Wi Ki Ngbọ !

Iya-Ajẹ kan pọ ẹiyẹ ajẹ ninu Şọọşi awọn aladura ni Mushin.

Ẹ ka iwe Irohin Imọlẹ Ọla Ọrọ pọ nibẹ. Tete ra ti ẹ, maşe jẹki nwọn o rohin rẹ fun ọ.

OLOTU

# IWE SI OLOTU

## Ọmọ Yoruba Ẹ Jẹ Ka Ronu

Olotu, Inu mi yio dun ti ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ ati alaka kẹglẹn lati ba awọn ọmọ Yoruba ilẹ kaarọ oojire sọrọ lori ipo ti a wa loni yi. Mo bẹ ẹyin ọmọ Yoruba pupọ ki ẹ jẹ ki a ronu wa wo daradara ki a si mọ ibti a nlọ.

Gẹgẹbi gbogbo enia ti mọ, pe ni gbogbo orilẹ ede Naijiria Yoruba ni o gbajumọ julọ gbogbo nkan lo si nlo daradara fun wa tẹlẹ-tẹlẹ, ọpọlọpọ nkan daradara ni o si nti ọdọ wa wa ti o fi jẹ wipe awa ni a tun nfi ọ a han awọn Ipinlẹ ti o ku.

Ṣugbọn loni nkọ? Ẹ wo bi a ti ṣe nfi ara wa ṣe yẹyẹ larin awọn Ipinlẹ to ku? Gbogbo aṣiri wa ni a ti tu sita tan fun gbogbo enia.

Ẹ si tun wo bi a ṣe pin ara wa kakiri pẹlu aini iṣọkan larin ara wa? Awọn kan nṣe ẹgbẹ ọmọ Odudiwa awọn kan nṣe ẹgbẹ ọmọ "Ọlọfin" Bẹni a si tun pin ara wa si orişirişi ẹgbẹ oşelu, Njẹ ẹ lero pe iru ipo ti a wa loni yi wa dara bi? A si tun nṣe ara wa nitori owo ati ipo.

Gbogbo awọn ara Ipinlẹ ti o ku ni nwọn ni ifọwọsowọpọ larin ara wọn Ṣugbọn ti awa Yoruba ko ri bẹ, Ibo Apapọ lo ku si dẹdẹ yi, ẹ jẹ ki a ṣe ara wa ni ẹyọ kan nitoripe ti a ba sowọpọ a ko ni le fi ika abamọ bọnu.

Ẹ jẹki a fi oju inu wo abayọri enia kika to kọja yi, nje ti awọn ọmọ Yoruba ti o wa labẹ akoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ba papọ mọ wa pẹlu Ipinlẹ ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ ati ti ilu Eko ba papọ mọ wa ṣe ẹ mọ wipe awa ni iba pọju Ipinlẹ to ku lọ?

Ẹ wo ẹgbẹ titun N. N. D. P. ti nwọn da silẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, gbogbo wa la mọ pe ara ẹgbẹ N P C ni wọn, ipo wo ni ẹ fẹ ki Yoruba wa nigbati ẹgbẹ DẸMỌ ba papọ mọ N P C Nitorina Yoruba ẹ jẹki a ronu wo.

Olotu, mo dupẹ o,

Emi ni,

S. O. Famiyẹsin,

MUSHIN.

## E la eyi yemi

Ẹ jọwọ ẹ gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe nyin ti nta bi Akara gbigbona lati bere ọrọ kekere yi lọdọ awọn ọjọgbọn ti nka loju mejeji lati bere ọrọ mi yi lọwọ nwọn.

Ni ilu kan awọn ọrẹ mẹta kan wa ti nwọn ngbe pọ, nwọn si fẹran ara wọn.

Ninu ilu yi, Ọba kan wa ti o ni ọmọbinrin kan ti ko ni ọkọ Ni ọjọ ti awọn Babalawo difa fun Ọba na pe, a fi ti o ba le ri rin gbado kan ni ilu rẹ yio le toro.

Ọba pe gbogbo ilu jọ oni enikeni ti oba le mu erin agbado kan wa ni yio fẹ ọmọbinrin kan soso ti on ni. Beni ilu yi kikiyanri ati okuta ni.

Ni awọn ọrẹ mẹta yi ba mura ẹnikan ra ẹyọ agbado lọ ekeji wa ilẹdu lọ ati ẹkẹta wa omi lu nwọn bamu ilẹdu nwọn da sinu yarin nwọn gbin ẹyọ agbado na sibẹ ni nwọn ba nbu omi si. Nigbati agbado yi dagba ẹyọ-erin agbado kan soso ni ẹyọ.

Tani ọ ye ki o fẹ ọmọ ọba ni-nu awọn ọrẹ mẹta yi?

Olotu Ajinde ara yio ma jẹ

Emi ni

O. Adewara

Igbomina.

## Awọn Afọju Pọ L'Eko

Ẹ dakun ẹ gba mi ni aye lati ba Ijọba Ibilẹ Eko sọrọ lori awọn afọju ti o pọju ẹniti ko fọju lo ni ilu Eko, ako tilẹ ri aye rin mọ rara ni ilu Eko, loju gbogbo awọn alejo ti o ba de ola ilu Naijiria, afọju ni yio ma pe gbogbo enia ti o wa ni Naijiria, Yoruba lo ma npa owe kan pe, ẹnikan ni o ge owo ti nwọn si nṣe ilo na ni ilu ake agewọ di oni oloni.

Inu wa yio dun ti Ijọba Ibilẹ Eko ba le ba wa ko awọn Mallam afọju kuro larin ilu Eko ati orisirisi bi eyiti apa rẹ ti ge ati bẹẹbẹ lọ.

O ti di asa wọn alarun wọnyi lati ma wa si ilu Eko, omi an dẹte ẹniti oba lọ si ọna Arọloya ni ẹba ile ẹkọ to wa nibẹ, ọkankojọkan ni nibẹ ti gbogbo rẹ nru bi ile igbẹ ti enia ko ni le kọja ki aya ko mọ rin oluwere.

Nibi ẹrọ omi Ijọba to wa nibẹ ni nwọn ti nbu omi inu, nwọn ko ni abọ lati fi mu omi ẹlomiran ngbe enu bọ omi na pelu.

Inu wa yio dun ti Ijọba Ibilẹ Eko ba le ba wa ko gbogbo wọn si ibikan ti nwọn yio mọ gbe.

Olotu ẹ ku iṣẹ o,

Emi ni

S. A. Ọmọniyi

EKO

## Oke-Ọla Nfẹ Atunṣe Ijọba

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ ti njade lojojumọ lati kesi awọn Ọmọ Oke-Ọla ki wọn jẹ ki afọwọsowọpọ fun idagbasoke ilu wa.

Gbogbo ọna to wa ninu wa ni ko dara mọ oju ọna ti o gba ilu wa kọja ti ba jẹ kọja ti tuose gbogbo oju ọna wa loyẹ ki o ni ọda bi awọn oju ọna to wa ninu ilu yoku

Ilu Oke-Ọla ko kere larin Ipinlẹ Ariwa ilu ti ko tobi to ilu wa ni Ipinlẹ Ariwa ni ina mana-mana, ẹrọ omi, gbogbo oju ọna wọn si ni ọda ati orisirisi awọn nkan meremerẹ.

Eyiti ojẹ nkan pataki ni ti ile-iwosan ti a ati nṣe wahala si lati ọdun gbọrọ sẹhin sibẹsibẹ a ko gbọ nlọ nbọ re mọ rara beni nigbagbogbo ni awọn olotu ijọba mọ da wa lọkan le awọn yio kọ ile iwosan nla kan fun ilu wa.

Ijọba Ipinlẹ Ariwa ko ṣe nkan kan to dara fun wa rara, ki owo ori ti a nna nikan ni a nri, a ko mọ ibiti nwọn nna owo na si rara

Mo dupẹ olotu fun aye ti ẹgba mi.

Emi ni,

Olaniyi Adewaa

ESIẸ.


BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495

Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

OWO *PỌKU* NI A SI *NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo iwọ o ri iyatọ*



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ṣe şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa ni ọkun losan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn a lera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de ,adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun pata-pata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igba-dun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:a

Waterloo Medicine Store

8, Palm Church Street, Lago-

ADEDUN CHtEMIST

14' Wakeman Sreet, Yaba

# Işẹ Owọ Ha Pe Ju Işẹ Iwe Kika Lọ Bi?

Lati Owọ:— Latifu Babalola, Akọwe Agba, Ẹgbẹ Imọle Aiye

Mo ki gbogbo ẹnyin ẹlẹgbẹ mi, e ku deede wo yi ẹ ku ojọ mẹta loni ngo se alaye fun gbogbo ẹnyin ọdọ orilẹ-ede Yoruba lati mọ nipa ohun ti awọn Oyinbo npe ni "Debate" eyiti itumọ rẹ l'ede abini bi wa a ma jẹ ariyanjiyan Nitorina a dun mọ mi ninu pupọ ti ẹ ba le fi ara balẹ ba mi ka ọrọ na ni aka yeke ko ni kun to ti ngo ba sọ siwaju fun yin pe emi ko ni şe alaye pupọ nipa ẹkọle oke yi, sugbọn ena ti o ba wa si ile-işẹ Irohin Imọlẹ ni ọjọ Sunday ti o nbọ yi lati wa

wo nigbati awọn ẹlere ẹgbẹ ariyanjijan ti ẹgbẹ Imọle Aiye yio gbe şe ere yi yio ma gbọ pupọ alaye lati ẹnu awọn enimọ ti yio sọrọ ni ọjọ na nitorina mo fi eyi kesi iwọ ọmọ ẹgbẹ tabi gbogbo enia lati tete de, ki ẹ si ma şe alai ko wa, nitori ọpọlọpọ ọgbọn ati ijinlẹ Yoruba ni ao ri kọ ni ibẹ.

Ere ariyanjijan jẹ ayọ ati ma sọrọ lori ohun kan eyiti awọn apakan yio ma si ro pe on ni o dara ti apa keji yio si ma şe atako rẹ, ki ere na to bẹrẹ ohun ti awọn ti o ba fẹ şe ni lati kọkọ şe [illegible] lati yan alaga, eyiti yio ma pe ẹnikankan ti o ba kan lati wa sọ tire,

Awon enia ti nwọn yio yan le jẹ marun ni apakan kan ekini yio sọrọ gbe, ekeji yio tako pe ko dara fun apẹrẹ awọn apakan yio sọ pe işẹ owọ peju işẹ iwe kika lọ, eyi ni pe onişẹ owọ lori owo ju ti gbogbo nkan si ndan nigbakugba ju onişẹ akọwe apakeji a sọ pe işẹ iwe kika pe ju işẹ owọ lọ, eyi ni pe ti o ba kawe mẹfa tabi mejọ ko si ma şişẹ ni ile işẹ nla gẹgẹbi akowe, tabi oniwe Irohin jẹ pe iwe ni o fi nşişẹ, o pe ju owo tabi o dara o si nfun ni ọpọlọpọ owo lati fi ma şe ọmọ jaiyejaiye ju işẹ ọwọ lọ paapa wa tete di ọlowo.

Lẹhin ti onikaluku ba ti sọrọ tan alaga yio wa tun pe awọn enia miran lati wa sọrọ lori eyiti on. Lẹhin ti awọn enia ma ba sọrọ tan nwọn le jẹ mejimeji ni apakankan awọn wa dibo eyiti o ba wọle, ni alaga yio fi ara mọ ti o ba wun, on na le sọrọ nipa rẹ.

Ere yi si tun bọ ma fun enia ni ọpọlọpọ imọ ati ẹrọ nlanla.

Nitorina ere yi si jẹ okan pataki ninu awọn ere ti ẹgbẹ yi ti pinnu lati ma şe, ki o le tun bo jẹki awọn ọmọ wa tun mọ ijinlẹ Yoruba dada.

Mo fi eyi kesi gbogbo ẹyin ọmọ karọ o jire lati tete wa di okan ninu ọmọ Imọle, nitori aye yi wa fun ẹnikẹni lati di ọmọ ẹgbẹ.

Laipẹ, ẹo tun gbọ irohin ẹgbẹ yi nipa awọn ere yoku ti a fẹ şe gẹgẹbi ere boolu, awọn ere ile Yoruba bi i Ayo, Ludo, Draft ati be lọ, fun ilesiwaju ile Yoruba ti, a ti şe eto rẹ silẹ, ma jafara lati wa di ọmọ ẹgbẹ titan. Ẹgbẹ Imọlẹ Aye wa fun ọ, tete ma bọ.

Lakotan, Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ lati wa wo ere Ariyanjiyan yi ni ile işẹ Irohin Imọlẹ ni ọjọ Sunday ti işe ọjọ kọkanlelogbọn oşu yi ni agogo meji osan. Ao si ti tayọtayọ gba ọ nọ Ẹgbẹ itan.

Nitorina iwọ na le ma ro ohun ti o sọ ti o ba wa, boya nwọn le pe, iwọ na pe ki o wa sọ eyiti o ba ri pe o peju ninu mejeji.

## YE IRAWO RE

AQUARIUS (Jan 20-Feb18) Iwọ yio ri ere pupọ jẹ, bi o ba mu ẹrọ pupọ wa sode. Awọn obirin yio ni fẹ rẹ jojo

PISCES (Feb 19-Mar20) Arẹ ọkan yio mu, ailera yio si yọ ọ lẹnu mase şişẹ pupọ eyiti yio mu inu rẹ dun ran ti ara rẹ loni

ARIES (Mar 21-April 19) O mọ gẹgẹbi a ti le fun enia ni iroh nşugbọn ki o şe pari gbogbo işẹ ti o wa nilẹ irohin sugbọn ki o to se pari işẹ ti owa nilẹ iwọ yio ni rẹpọ iwọ yio si ri işẹ se mase şe ba ẹnikẹni ja

TAURUS (April20–May 20 Iwọ ẹri owo ati işẹ se ero inu rẹ dara. Ọkan rẹ si mọ eyi yio jẹki ẹri işẹ se ma se eyikeyi ninu ẹbi rẹ ja.

GEMINI May 21 - June:- Iranşẹ ti fẹ isimi, ma a şe ko ẹgbẹ buburu tọju işẹ rẹ, iwọ yio ba olorire enia pade ronu wo dara dara, koto dawọle eto miran lati şe

CANCER (June 22 – July 22) Nisisiyi itẹlọrun ti bẹrẹ si wọ işẹ şugbọn maşe pọn ara rẹ ni apọnbo, şọra lọdọ awọn enia buruku, ilọsiwaju yio wa fun ọ ninu owo ati işẹ, ere mbẹ fun ọ.

LEO (July 23 - Aug 22) Işẹ ti o kọ, ti o nşe lọwọ yi bẹrẹ si dagba soke, maşe gbagbe iya ti o ti jẹ kọja, jẹ ki inu awọn enia ma dun nipa tita wọn lọrẹ.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Arẹ yio mu ọ, şora ki o maşe ba ẹnikan tc jẹ kor kosun rẹ iyan rara, Işẹ rẹ yio ma ni ilọsiwaju, şugbọn ina si korikosun ẹgbẹ buburu.

LIBRA (Sept 23-Oct. 23) Ọrọ kekere kan ti mbẹ nilẹ yio pari loni, şugbọn ọpọ isoro ni yio tẹ ọgbọn lati ẹdọ rẹ wa, mu suru, maşe da ri ọrọ ọlọrọ

SCORPIO (Oct. 23-Nov. 22) Ọjọ oni lo yẹ ki o pari ede kẹyede ti o wa nilẹ, fetisi imọran ti ẹlomiran

SAGITTARIUS (Nov. 23-Dec. 22) Ọjọ oni ni ọjọ ti o ni lati gbọ ti ara rẹ, iwọ yio ri owo to fi şe faji şugbọn ọrọ iwọ pẹlu obinrin kan ko ni wọ ara wọn. Maşe wa ingto loni.

CAPRICORN (Dec 23-Jan. 19) Maşe işẹ Samuẹl loni, gbogbo işẹ rẹ ati owo ni ire wọ inu rẹ maşe wahala pupọ


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise MODUPE PRESS*

*Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupe Printing Press**

16, Bamgbose Street,
Phone 21985, Lagos


**[illegible] ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Ki ẹ Si Ma Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu**

# Ọtẹlẹmuyẹ Nki Nyin o

Ẹ ku afẹfẹ yi o ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ, gbogbo nyin ni mo ki la da ẹnikan si O. Olọun iba rẹ o.

Mo ti ṣe ileri mo si ti pinnu lati ba awọn Woli eke kanlẹ dẹnundẹnun, ngo si ṣe bẹẹ lagbara Oluwa.

Ṣugbọn ikilọ ni ngo ṣe fun awọn ọkọ ti nwọn ngba iyawo wọn laye lati mi a lọ jọsin lọdọ wọn. Ẹ maṣe gbogbe pe:

Ekini: Awọn Woli eke ti mo nwi yi ni i ma a furara wọn fun obinrin ti o ba wa ọmọ de ọdọ wọn loyun

Ekeji: Awọn Woli eke na ni i mọ ale obinrin, ti nwọn tun ngmọ ọkọ ọmọ

Ẹkẹta Awọn Woli eke na ni eṣu lalu ekeri-ọkọ ode ki ile onile tu,

Ẹkẹrin:- Awọn ni nwọnsi ngbe baba kọlu ọmọ, ti nwọn si ngbe ọmọ kọlu baba.

Ẹkarun:- Awọn ni nwọn nṣọ olowo di talaka ọsanganngan.

Ẹkẹfa:- Awọn ni nwọn nsọ Ọlọmọ di agan.

Ekeje: Awọn ni nlo afọṣẹ ti odaju hanhanun lati gba owo lọwọ awọn ọmọ ijọ wọnati orisirisi iṣẹ buburu miran ti Ọlọrun ko ni inu didunsi Ẹnyin onkawe Irohin Imọle, ẹṣọra nipa nwọn gidigidi ki nwọn ma ba ọ yin di ẹdun arinlẹ.

Ẹo tun ma gbọ nipa awọn woli gba aṣọ gb'abẹla ati ẹran.

Eyi nilati kede fun ẹnyin onkawe *Irohin* Imọlẹ gbo pe, emi Ọtẹlẹmuyẹ fẹ rin ajo lọ si Ipinlẹ *Iwọ* Orun laipẹ yi, lagbara Oluwa ni ati Ịẹhin Odumare e o ma a gburo bi gudu gbe yi ti ma ja lati "Westa Rigiọnu", ṣugbọn ki ngto kọja lọ nko tun ni ṣalai mẹnuba ọrọ dẹreba ti nwọn ngna Mushin si Itirẹ, sibẹsibẹ nwọn koiti gbọran o nitoripe akun-faya ni mọto won si nkun. Ti mo ba wo sun titi Ọsẹ yi, ngo kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti awọn Ọlọpa a numọto ko ba dako fun wọn.

### WOLEWOLE NKỌ?

Emi Ọtẹlẹmuyẹ f'ẹnu sọ. mo fẹrẹ tun fi furọ sọ nipa pe ki awọn Wolewole Mushin maa mojuto ilu Itirẹ nitoripe jaburata ni koto iku wa nibẹ ẹnyin paapa si ti mọ daju pe, ibiti koto ba wa adagun omi ko ni wọn nibẹ ibiti adagun omi ba wa ẹfọn ko ni wọn nibẹ, ib ti ẹfọn ba si wa, iba ponju ponju ko ni wọn nibẹ.

Mo tun fi eyi kede fun awọn Wolewole Mushin ki nwọn dabo ilu Itirẹ, ki nwọn si bẹrẹsi ma a gbe awọn ti o ba lodi si ofin ile ra jantojanto.

Ti nko ba si ri kọrọ kan ninu ọsẹ yi, ngo kan si Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lori ọrọ na o.

Emi Ọtẹlẹmuyẹ ki gbogbo yin pe, o digba kan na o, ki Oluwa dakun maṣe eyi ni aṣemọ fun wa o.


BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ERỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo H o ri iyatọ*


## Yoruba Debate

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ẹgbẹ Ariyanjiyan (Debate Club) ti Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye yio ṣe ariyanjiyan lori Iṣẹ ọwọ ha pe ju Iṣẹ Iwe Kika lọ bi ? ni ọjọ Sunday ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu yi ni deede agogo meji ọsan (31/5/64).

Nitorina a pe gbogbo enia lati wa wo ere na. A tete de ṣe pataki.

LATEEF BABALỌLA
Akọwe Agba


## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan Erok wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo

## Apejuwe Ile Isẹ Wa

Ẹ wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ti oba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O A FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 20/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 25/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 5/- |
| Iwe Ilana Yanrin tite ati Etutu Şişe | 20/- |
| Iwe Afọṣẹ Isẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Iṣẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6d |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/- |

BERE EGBOGI PATAKI YI TINWỌN NPE NI:—

# "Figurana"

Jẹ ojulowo egbogi ti awọn Jamani ṣẹṣẹ ṣe iwadmi fun awọn ti o ba sanra tabi ti o ba ,TOBI' ju lati ri mu ki nwọn le fi jọnku lai si wipe nwọn ma ka ewọ onjẹ ti nwọn yio ma a jẹ rara, bẹ sini ko lewu ni li o fun enia rara, yala Ọkunrin tabi Obinrin.

Ki enia sanra, gborin, tabi ki o tobi pupọju, ki nṣe ohun ti o dara rara, ọpọlọpọ amodi ni onko ba, ania bi Lakuregbe, Aiko le gbera nilẹ bi o ba joko Aiya lile kiki tabi jija nigbana, Aiko le mi kan lẹ daradara Ara wiwo, tabi wiwuwo, Emi mimi họ-họ ti orişirişi amọdi miran pẹlu.

Sa dan Igo rẹ kan wo, Iwọ y'io ri ayipada ati alafia yio desi Bere ni Ṣọbu awọn Elegbogi Jamani ni igboro Ilu Eko.

PILENAB MIXTURE',

Egbogi olomi dara julọ fun awọn ọmọde ti jẹdijẹdi bi aiko gbọnse dede ba nyọ lenu bere rọ ni
WATERLOO MEDICINE STREES
'AFAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No. 705 WEDNESDAY MAY 275 1964 (2D)


## Alhaji Kan Sọ Ọgba-Ẹwọn Di Ilé!

MAKURDI:— Kẹkẹ pamọ gbogbo enia ti nwọn wa ninu ile ẹjọ lenu nigbati awọn Ọlọpa mu apẹlẹwọn Ọdaran kan, Alhaji Jida ... Ọdun mejilelogbọn wa siwaju adajọ ile ẹjọ ... Ọjọ Iṣẹgun ti iṣe Ọjọ kẹrindinlọgbọn Oṣu yi.

Alaye ti Ọlọpa ti o ba Ọdaran Alhaji na ṣẹjọ ṣe niwaju adajọ ni pe, ni Ọjọ keji Oṣu yi, ni Alhaji na lọ Si Tesan Ọkọ reluwe, Makurdi, ti o si lọ duro de Ọkọ Kano ti mbọ.

Nigbati o de idi Ọkọ na, o ṣe bi ẹnipe on wa pade ero kan ni Tesan, o si Ọgbọn sunmọ ọdọ Ọgbẹni Raphael Ubani. o mu Ọbẹ biledi kan lọwọ o si fi rẹ apo ẹwu Ọgbẹni Raphael. Ọgbẹni Raphael ko mọ, ṣugbọn awọn ti nwọn nwo Ọdaran Alhaji na nitori ni, nwọn kigbe ti nwọn si mu Alhaji na.

Ọlọpa na tun ṣe alaye pe, Alhaji na ti lọ si ẹwọn nigba mẹdogun ri, nigbati adajọ na bere lọwọ Alhaji na Ohun ti o fẹ sọ, Alhaji na wa bere, lọdọ Adajọ pe, " o bere pe ?iru Ọgba ẹwọn ni nwọn gbe bi mi ni"? adajọ na fesi pe, on ko mọ ṣugbọn boya, o ti sọ Ọgba ẹwọn di ile rẹ "

Lẹhin eyi ni adajọ ba ni ki o lọ si ẹwọn Ọdun mẹta lafarabara.

# ỌLỌṢA KAN GUN OLOWO L'ỌBẸ L'ORI!

AKURẸ, Gbogbo awọn ero ti o wa ninu Ile ẹjọ kekere Akurẹ ni nwọn ya ẹnu silẹ ti nwọn ko si le pade mọ nigbati awọn ọlọpa de ọdaran ọlọṣa kan, Umoru Haruna, nigbekun wa siwaju adajọ fuu ẹsun alọnilọwọ gba, agunbẹ ati igbiyanju lati pania ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi.

Ọga awọn ọlọpa Akurẹ Ọgbẹni Richard Oyelọwọ ti o ba ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye fun ile-ẹjọ pe, nigbati Ọgbẹni Ganiyu Akanmu ta ẹran rẹ tan ni ọja ti o si nko owo ẹran ti o ta lọ si ile, ni awọn ọdaran ọlọṣa meji kan ba lọ duro de ni opopo Salvation, lati gba ẹwo ẹran ti o ta lọwọ rẹ.

Nigbati awọn ọdaran na sare lọba Ọgbẹni Akanmu lọju ọna, nwọn bi lere pe, "owo rẹ ni o fẹ padanu tabi ẹmi rẹ, o gbọdọ mu ọkan ninu mejeji"

Ọlọpa na ni ki Ọgbẹni Akanmu to sọrọ, ni Haruna ti yọ ọbẹ jade ninu apo, bi Ọgbẹni Akanmu ti ri ohun ti awọn ọlọṣa na fẹ ṣe ni o ba bẹrẹsi kigbe "ole! ole!" ṣugbọn ki o to kigbe ole, ni Haruna ti gun ni ọ b ẹ ni agbari, o tun gun ni ọbẹ ni ejika.

Ki awọn enia to de Haruna ti ti ọwọ bọ inu apo ẹwu agbada,

Akanmu o si ko pọnun mejindinladọta (£48) ti o wa ninu agbada rẹ.

Sugbọn bi awọn ọdaran mejeji na ti ṣe iṣẹ ibi ti nwọn fẹ ṣe tan, ti nwọn si fi ọkunrin na silẹ ninu agbara ẹjẹ, ni awọn aladugbo ba sare jade awọn Ọlọṣa mejeji si salọ.

Ṣugbọn nigbati awọn enia nle awọn Ọlọṣa na lọ, Haruna ti gun Akanmu lọbẹ ni ọwọ awọn enia na tẹ, ẹnikeji rẹ si salọ.

Lẹsẹkẹsẹ n nwọn mu ọdaran na lọ si Tesan ọlọpa ti nwọn si fi si itimọle.

Nigbati awọn enia na rojọ ohun ti ọdaran na ṣe ni awọn ọlọpa ba lọ gbe Akanmu kuro ninu agbara ẹjẹ ti wọn si gbe lọ si ile-iwosan fun itọju.

Adajọ ko ti le gbọ ọrọ lẹnu ọdaran na, ti o fi paṣẹ pe, ki awọn ọlọpa lọ fi pamọ si itimọle titi di ọjọ ti on yio ṣe ẹjọ na o si tun paṣẹ pe ki awọn ọlọpa maa lọ wa ẹnikeji rẹ ki o to di ọjọ ti on yio nṣe ẹjọ awọn mejeji papọ.

### LATI OJU EWE KINI

gboro-Ẹhin ipade na ni ana pe,-Ijọba fẹ ṣe ofin pe awọn Oṣiṣẹ ko gbọdọ da iṣẹ ... ibi irohin ẹkunwo na tẹ wọn lọrun tabi ko tẹ won lorun nigbati o ba jade.

A gbọ pe ofin yi ni apapọ Ijọba ... ṣe ti ko jẹki nwọn tete gbe abayọri Igbimọ oluwadi na jade lati ọjọ yi.

Ọgbẹni Goodluck sọ fun Ejon'gboro pe, "Nigbati Ijọba ko ti pari gbogbo ko ohunti nwon fẹ ṣe, kini Ọgbẹni Ọbande nwa lo si ilu rẹ lọsẹ to koja yi? Kini Oloye J. M. John son wa lo si Amẹrika ni gbati ko ti pari iṣẹ rẹ gẹgẹbi Minista Alamọjuto awon oṣiṣẹ?"

Ni ipari, Ọgbẹni Goodluck wa bere pe, "Tabi awọn Minista wọnyi tile gbagba pe awọn ara ilu ni o yan awọn si aye ti awọn wa ni ? "

Awọn Asiwaju Igbimọ ẹgbẹ Awọn Oṣiṣẹ na yio ṣe ipade kan ni Owurọ yi, Ohun ti nwọn ba si ṣọ ninu ipade na, ẹo ma a gbọ ninu iwe irohin wa.


## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, ọrẹrẹ lukuluku onigbameji tabi a ı p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ apo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọna-ọfun didun, ati orişirişi omirau pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos
NIGERIAN MEDICINE STOE
Tinubu Square Lagos.


## Ẹgbẹ Ọdọ Afẹnifẹre Fẹ Ṣe Ipade

MUSHIN: Ni deede agogo mejila ọsan ana ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi ni irohin kan wa lati Ile-iṣẹ ti nghẹnuṣe fun ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group Bureau of Publicity) pe, ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre yio ṣe ipade kan ni irọlẹ oni ọjọ "Ru ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn ni nọmba 23, Awoyọkun Street Mushin.

Gẹgẹbi irohin na, a gbọ pe ni deede agogo marun irọle yi ni ipade na yio bẹrẹ.

Ninu awọn enia jankanjankan ti yio wa sibi ipade na ni irọlẹ yi ni, Iyaafin Fẹmi Pearse, Oloye G. B. A. Akinyede, Ọgbẹni Bisi Ọnabanjọ, Oloye Akin-Olugbade, Ọgbẹni Oluşọji Odunjọ ati awọn miran.

Irohin fi ye wa pe, ohun ti awọn ẹgbẹ na fẹ ṣe ipade le lori ni ọgọọrọ enia ti o nwo iru ẹgbẹ na lati bi oṣu diẹ sẹhin wa.

Oniwe irohin wa Ejongboro yio lọ sibẹ ẹo si gbọ gbogbo ohunti nwọn ba sọ.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street Lagos Phone 21985
Editor;- TUNJI ADEOSUN 45, C ampbell Street, Lagos 275/64